# Àfìhàn Àwọn Ọlọ́pàá Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà Nínú Àṣàyàn Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ

Justina Ọlábọ̀wálé Adams
Department of Yorùbá, School of Languages
Federal College of Education, Òṣíẹ̀lẹ̀, Abẹ́òkúta
Ògùn State, Nigeria
olusanyajustinaolabowale@gmail.com

## Àṣamọ̀

Àjọ ọlọ́pàá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà jẹ́ àjọ tí a dá sílẹ̀ láti máa mú kí omi àmù ìlú tòrò. Onírúurú iṣẹ́ akadá tó ti wáyé lórí wọn bu ẹnu àtẹ́ lù wọ́n. Àmọ́, àwọn òǹkọ̀wé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ èdè Yorùbá nínú ìwé wọn fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, àwọn ọlọ́pàá ní àwọn ìpènijà tó ń bá wọn fínra lábẹ́lẹ̀; àwọn ìpènijà bẹ́ẹ̀ ni pépà yìí dá lé. Tíọ́rì Sosíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ Yorùbá ni a lò. Ìwé ìtàn àròsọ marun-un, eré-onítàn mẹ́fà àti ewì meji la ṣàtúpalẹ̀. Àwọn ìpènijà tí a hú jáde ni: ọ̀rọ̀ akọ-n-bábo, àìní ìlapa ètò òun irinṣẹ́ tó mú yányán, àìsí ètò amáyédẹrun tó fún àwọn ọlọ́pàá, irú ìjọba tàbí àwọn olórí ọlọ́pàá tó wà lóde àti ìwà òbìlẹ̀jẹ́ láàárín àwọn ọlọ́pàá fúnra wọn. Iṣẹ́ yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé tí a bá wá ojútùú sí àwọn ìpènijà òkè yìí, àjọ̀ ọlọ́pàá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà yóò túbọ̀ lè ta bíọ́bió sí i lẹ́nu iṣẹ́ wọn.

## 1. Ìfáàrà

Àjọ ọlọ́pàá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà jẹ́ ọ̀kan lára àjọ tó ń gbófinro ní ilẹ̀ Nàìjíríà. A dá a sílẹ̀ ní pàtó láti máa dènà ìwà ọ̀daràn, tọpinpin àwọn ọ̀daràn, dáàbo bo dúkìá àti ẹ̀mí, àti láti máa rí i pé omi àmù ìlú tòòrò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Onírúurú iṣẹ́ akadá òun ìjíròrò ló ti wáyé lorí wọn ṣùgbọ́n, ó ṣe ni láàánú pé ọ̀pọ̀ àwọn iṣẹ́ yìí bu ẹnu àtẹ́ lù wọ́n ni pé, wọn kò dáńgájíá tó lẹ́nu iṣẹ́ wọn (Brownson 2012:5). Àmọ́, ìwádìí síwájú sí i fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn ìpènijà kan wà tí ó ń bá àwọn ọlọ́pàá yìí fínra lábẹ́lẹ̀, èyí tó sì kún ìdí tí wọ́n fi fẹ́rẹ̀ẹ́ dàbíi aláìmọ̀ọ̀ṣe. Ọ̀pọ̀ àwọn ìpènijà yìí ni àwọn òǹkọ̀wé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ èdè Yorùbá tẹ́ pẹpẹ nínú ìwé wọn pẹ̀lú àwọn ọnà àbáyọ, èyí sì ni pépà yìí dá lé. Àwọn ìwé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ èdè Yorùbá mẹ́tàlá ni a ṣàyàn. Àwọn náà ni: ***Àjà l'ó lẹrù,***

*Oyin Inú Àpáta, Oorun orí kẹ̀kẹ́, Ọ̀dájú ni wọ́n,* àti *Atítẹ̀ẹ́bí*, (Ìtàn àròsọ); *Oyíndàmọ̀lá ọmọ ọlọ́rọ̀, Ọlọ́run ò màwàdà, Olúwa ló mẹ́jọ́ dá, Gbamúgbamù, Ayé yẹ wọ́n tán, Iná ràn;* (Iwé eré-onítàn); *Aṣọ ìgbà àti Orin Ewúro*, (Ewì). A yan àwọn ìwé yìí láàyò nítorí pé, wọ́n kún fọ́fọ́ fún akitiyan òun iṣe àwọn ọlọ́pàá lóríṣiríṣi. Nínú pépà yìí, a ṣàfihàn àwọn ìpenijà ọ̀hún pẹ̀lú èròǹgbà pé tí a bá lè wá ojútùú sí àwọn ìpènijà náà, àjọ̀ ọlọ́pàá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà yóò túbọ̀ lè ta bíọ́bió sí i lẹ́nu iṣẹ́ wọn, ohun gbogbo yóò sì sùn wá bọ̀. Tíọ́rì soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ ni a lò gẹ́gẹ́ bí férémù láti gbé iṣẹ́ ìwádìí yìí ró nítorí pé, tíọ́rì yìí jẹ mọ́ ìwádìí tàbí ìtọpinpin àwùjọ bẹ́ẹ̀, inú àwùjọ ni àwọn ọlọpàá wà, àwújọ ni wọn sì ń ṣiṣẹ́ sìn.

## 2. Àjọ Ọlọ́pàá Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà

Ní ọdún 1829 ni a fẹ́rẹ̀ lè sọ pé àwọn ẹ̀ṣọ́ ìgbàlódé tí à ń pè ní ọlọ́pàá gbòde kan. Ọ̀gbẹ́ni Robert Peel tó jẹ́ Akọ̀wé Àgbà ní orilẹ̀-èdè Gẹ̀ẹ́sì ló sì ṣe agbátẹ̀rù rẹ̀ nígbà náà. Ṣaájú àsìkò ìjọba ìmúnisìn ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni àwọn ẹ̀yà ibẹ̀ ti ní àwọn ọ̀nà tí wọ́n ń gbà láti mú kí ohun gbogbo tùbà tùṣẹ (Olongha, 2016; Àrẹ̀mú 2009 &; Àrẹ̀mú 2014; Búsàrí 2015; àti Àjàyí (2016). Fún àpẹẹrẹ, ní ilẹ̀ Yorùbá, wọn ti ni àwọn Ẹ̀ṣọ́ láàfin tí wọ́n ń pè ní 'Akọ́dà', àwọn wọ̀nyìí ni a padà wá yí orúkọ wọn sí 'Ọlọ́pàá'. Àwọn ní Aláṣẹ Ìbílẹ̀ (Native Authorities) àti Ọlọ́pàá Ìbílẹ̀ (Local Government Police Force) nígbà náà (Àrẹ̀mú 2014). Ní àárín oṣù kẹrin, ọdún 1861 ni a fẹ́rẹ̀ lè sọ pé ìgbìyànjú àkọ́kọ́ láti dá Àjọ Ọlọ́pàá ìgbàlódé sílẹ̀ lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà wáyé. Ọ̀gbẹ́ni Beecroft tó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn Aṣojú orílẹ̀-èdè Gẹ̀ẹ́sì sórílẹ̀-èdè Nàìjíríà ló sì ṣe agbátẹ̀rù rẹ̀. Nígbà náà, wọ́n pè wọ́n ní 'Consular Guard', ọgbọ̀n sì ni àwọn ẹ̀ṣọ́ tí wọ́n kó jọ náà. Àyípadà díẹ̀ dé bá a ní ọdún 1863 sí 1879. Ọdún 1879 yìí ni wọ́n yí orúkọ náà si, 'Hausa Constabulary' tí wọn sì yan Ọ̀gá Ọlọ́pàá Àgbà láti jẹ́ olórí wọn. Ní ọdún 1893, a ṣẹ̀dá Àjọ Ẹ̀ṣọ́ mìíràn ní ìlànà 'Hausa Constabulary', a pè é ní 'Niger Coast Constabulary' bẹ́ẹ̀ ni a tún ṣẹ̀dá òmíràn ní 1888 tí a pè ní 'Royal Niger Constabulary'(Àrẹ̀mú 2014).

Àrẹ̀mú (2014) jẹ́ ká mọ̀ pé oṣù kìíní, ọdún 1896 ni wọ́n dá Àjọ Ọlọ́pàá sílẹ̀ ní ìpínlẹ̀ Èkó, ìyẹn 'Lagos Police Force'. Nígbà tí wọ́n wá pín orílẹ̀-èdè Nàìjíríà sí Ìlà-Oòrùn àti Ìwọ̀-Oòrùn ní ọdún 1900 ló wá mú kí wọ́n pín Àjọ Ẹ̀ṣọ́ 'Royal Niger Constabulary' sí Àjọ Ọlọ́pàá Ìlà-Oòrùn (Northern Nigeria Police Force) àti 'Northern Nigeria Regiment'. Àjàyí (2016) ṣàfihàn rẹ̀ pé, ọdún 1906 ni Àjọ 'Lagos Police Force' àti díẹ̀ lára 'Niger Coast Constabulary' náà wá di Àjọ Ọlọ́pàá ti Ìwọ̀ Oòrùn Nàìjíríà (Southern Nigeria Police) tí àwọn Ẹ̀ṣọ́ tó kù nínú 'Niger Coast Constabulary' si di 'Southern Nigeria Regiment'. Ní oṣù kẹrin ọjọ́ kìíní, ọdún 1930 ni wọ́n wá jan àwọn Àjọ yìí papọ̀ láti di Àjọ Ọlọ́pàá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà gẹ́gẹ́ bí a ti rí i lónìí tí olú ile-iṣẹ́ wọn sì wà ní ìpínlẹ̀ Èkó nígbà náà. Ọ̀gá Ọlọpàá Àgbà nígbà náà ni C.W. Duncan (Búsàrí, 2015:4)

nígbà tí Louis Orok Edet jẹ́ ọmọ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àkọ́kọ́ tí yóò jẹ Ọ̀gá Ọlọpàá Àgbà, (Àrẹ̀mú, 2009:8; 2014:7; Búsàrí, 2015:14). Ọdún 1954 ni Àjọ yìí di ti ìjọba àpapọ̀. Ọdún 1972 lásìkò ìjọba ològun lábẹ́ àkóso Ọ̀gágun Gowon ni a da àwọn Ọlọ́pàá Ìjọba Ìbílẹ̀ gbogbo mọ́ Àjọ Ọlọ́pàá tí wọ́n sì fi òfin 1979 àti 1999 (abala 214) gbe ìgbésẹ̀ yìí nídìí. Àwọn ojúṣe gbòógì Àjọ Ọlọ́pàá ni:

- ìdáábò bò àti ìpamọ́ ẹ̀mí òun dúkìá
- pípa òfin mọ́, mímú àlàáfíà jọba àti mímú ohun gbogbo lọ létòlètò.

## 3. Tíọ́rì Soṣíọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀

Tíọ̀rì ìfojú ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ wo lítíréṣọ̀ yìí jẹ́ àkànpọ̀ ẹ̀ka iṣẹ́ ìmọ̀ méjì ìyẹn 'Soṣíọ́lọ́jì' àti 'Lítíréṣọ̀'. Soṣíọ́lọ́jì ní i ṣe pẹ̀lú títọpinpin tàbí ṣíṣe àgbéyẹ̀wò àwùjọ ní ìlànà sáyẹ́ǹsì. Ó tún jẹ́ wíwo ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín àwùjọ kan àti àwọn iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ tó ń jáde níbẹ̀. Lítíréṣọ̀ ní tirẹ̀ jẹ́ àfihàn ohun tó ń ṣẹlẹ̀ lójú ayé, ó jẹ́ dígí tí a fi ń wo àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwujọ. Fọlọ́runṣọ (1999: 38) tilẹ̀ ṣe àfọ̀mọ́ rẹ̀ pé, lítíréṣọ̀ jẹ́ irinṣẹ́ tí a máa ń lò láti,

> *... expose, criticise, change and moderate the experiences of the people where it evolved".* (1999: 38)
> …ṣàfihàn ìwà ìbàjẹ́ láwùjọ, ṣe iṣẹ́ lámèyítọ́, ṣe àyípadà ọ̀tun tàbí, fi dínwọ̀n ìrírí àwọn ará ibi tí iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ kan bá ti jáde.

Lítíréṣọ̀ kò wà láti máa bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà ìbàjẹ́ àwùjọ nìkan ṣùgbọ́n a tún máa ṣàfihàn oríṣiríṣi àwọn òpó tó so àwùjọ ró (social institutions*)*. A tún máa ṣàfihàn àwùjọ fúnrarẹ̀ àti àwọn ènìyàn inú àwùjọ ọ̀hún (Bọ́láríǹwá, 2013: 36).

Bọ́láríǹwá (2013: 15) ṣàlàyé síwájú sí i pé lítíréṣọ̀ a máa yàtọ̀ láti àdúgbó kan sí òmíràn nítorí àwọn iṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, àyíká àti ìmọ̀ tẹkinọ́lọ́jì tí àwọn òǹkọ̀wé ń wò tàbí ṣàfihàn nínú iṣẹ́ wọn náà a máa yàtọ̀ láti àwùjọ kan sí òmìíràn. Welleck àti Warren nínú (Àjàní, 2011:9) ṣàlàyé pé, làìṣe àní àní, ìbáṣepọ̀ tó lóòrìn ló wà láàrin Soṣíọ́lọ́jì àti Lítíréṣọ̀ níwọ̀n ìgbà tó ṣe pé àwùjọ ni Soṣíọ́lọ́jì máa ń tọpinpin tó sì tún jẹ́ pé, lítíréṣọ̀ pẹ̀lú orísun àwọn ibi tí ó ti máa ń rí àwọn kókó ọ̀rọ̀ rẹ̀ gbà jọ. Bákan náà, àwọn méjèèjì yìí a tún máa ṣàgbéyẹ̀wò àyíká ọmọnìyàn, ìlakàkà rẹ̀ láti bá àwùjọ ọ̀hún dọ́gbá àti ìgbìyànjú rẹ̀ láti ṣe àwọn àtúnṣe ọ̀tun síbi tó bá yẹ. Ní ṣókí, kíkọ́ àkọ́jìnlẹ̀ nípa àwùjọ ni Soṣíọ́lọ́jì àti Lítíréṣọ̀ dá lé, nítorí náà, ni a ṣe ní ẹ̀kà ìmọ̀ tí à ń pè ní Soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ yìí (Bọ́láríǹwá, 2013: 36).

Lóòrèkóòrè ni àyípadà ọ̀tun máa ń dé bá àwùjọ, èyí a sì máa ń mú kí àwọn ọnà tí à ń gbà ṣàgbékalẹ̀ lítíréṣọ̀ rẹ̀ àti àwọn kókó-ọ̀rọ̀ inú rẹ̀ pàápàá yí padà. Irú àyípàda báyìí kìí ṣé lóri pe, àwọn ènìyàn ibẹ̀ yóò ti kàwé kún ìwé, ojú wọn yóò ti là sí i bẹ́ẹ̀ni, ìmọ̀ tẹkinọ́lọ́jì wọn pàápàá yóò ti tún múná sí i. Irú

ìbáṣepọ̀ báyìí láàárín àwùjọ àti soṣíọ́lọ́jì ni tíọ́rì soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ dá lé. Hyppolyte Taine, onímọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò arà ilẹ̀ Faransé kan ló rọ ọ̀rọ̀ yìí fúnra rẹ̀, tó sì ṣe agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí. Ó ṣe èyí láti lè máa lo ọgbọ́n ìwádìí tí à ń lò ní ẹ̀ka ìmọ̀ sáyẹ́ńsì náà fi ṣe ìtọpinpin lítíréṣọ̀ (Adéyẹmí, 2006: 29; Fọlọ́runṣọ́, 1999: 35).

Soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ a máa wo ipo òǹkọ̀wé ní àwùjọ àti ìbáṣepọ̀ òǹkọ̀wé ọ̀hún pẹ̀lú àwùjọ rẹ̀. A tún máa tẹpẹlẹ mọ́ ìbáṣepọ̀ tó wà láàárin iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ kan àti àwùjọ tó ti jáde wá, èyí wá ń ṣàfihàn pé, ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ni ó máa ń ṣatọ́kùn ohun tí à ń bá nínú iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀.

Ní àfikún, tíọ́rì yìí a tún ma ṣàgbéyẹ̀wò àṣà, ètò òṣèlú àti ètò ọrọ̀-ajé àwùjọ tí lítíréṣọ̀ ti jáde wá. Ní ìtẹ̀síwájú, Bámgbóṣé (2012) wòye pé, tíọ́rì yìí jẹ́ lára akitiyán àti mú kí ìwọ̀núbọ̀nú òun ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín lítíréṣọ̀ àti àwùjọ yé ni. Ó fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé iṣé ọnà lítíréṣọ̀ kan kò gbọdọ̀ wà dáńfó lóun nìkan, èyí ló dífá pé, a kò gbọdọ̀ dá ìtọpinpin rẹ̀ nìkan náà ṣe. Ìdí èyí náà sì ni pé, iṣé-ọnà lítíréṣọ̀ a máa dara dé àwùjọ. Onísẹ́-ọnà lítíréṣọ̀, fún àpẹẹrẹ, a máa dara dé àwùjọ, àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ibẹ̀, àwọn àyípadà tó dé bá a àti àwọn ìtàn rẹ̀ gbogbo ni a máa nípa tó lóòòrìn lórí irú onísẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀. Nípa báyìí, àwọn èrò rẹ̀ a máa wà ní ìbámu pẹ̀lú àwùjọ èyí tó bá ń gbé inú rẹ̀ (Bámgbóṣé, 2012: 25). Fọ́lọ́runṣọ̀ (1998: 39) sọ pé “lájorí iṣẹ́ sosíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ ni mímọ̀ ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín lítíréṣọ̀ àti àwùjọ”. Lọ́rọ̀ kan, a yan tíọ́rì yìí láàyò nítorí ó rọ̀ mọ́ ìtọpinpin àwùjọ, èyí ni yóò sì jẹ́ kí a lè ṣiṣẹ́ yìí délẹ̀délẹ̀ níwọ̀nba ìgbà tó ṣe pé ọlọ́pàá tí iṣẹ́ ìwádìí yìí dá lé jẹ́ ara àwùjọ tó sì tún jẹ́ pé, àwùjọ kan náà yìí ni wọ́n ń ṣiṣẹ́ sìn.

## 4. Ìpenijà tó ń dojú kọ àwọn Ọlọ́pàá bó ṣe hàn nínú àwọn àṣàyàn Ìwé Àpilẹ̀kọ Yorùbá

Onírúurú ni àwọn ìpènijà tó dojú kọ àwọn ọlọ́pàá gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú àwọn ìwé àṣàyàn lítíréṣọ̀ wa, lára wọn la ti rí:

### 4.1 Ìpènijà Akọ-n-bábo

Láti ìgbà tí a ti dáṣẹ́ ọlọ́pàá sílẹ̀ títí di kò pẹ́ kò jìnnà yìí, ńṣe ni àwùjọ rí iṣẹ́ ọlọ́pàá gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ọkùnrin (Àrẹ̀mú 2014: 23; Adégòkè 2014: 304). Nítorí náà ló ṣe jẹ́ pé ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ àjọ yìí, wọn kò gba obìnrin síṣẹ́ rárá (Àrẹ̀mú 2014: 23). Nígbà tó yá, wọ́n kàn gba díẹ̀ láti dín awuyewuye tó gbòde kan nígbà náà kú ni. Àwọn iṣẹ́ bí i iṣẹ́ akọ̀we, ṣíṣe àtẹ̀lé fún ọdaràn obìnrin, adárí ọkọ̀ lòjú pópó, olùṣewádìí ẹ̀sùn tó jẹ mọ́ ìbálòpọ̀ tí a fi kan obìnrin tàbí ẹ̀sùn tó jẹ mọ́ ìpẹ́ẹ̀rẹ̀ toun tí ká máa gbé ẹ̀rọ tẹlifóónù tí ìpè bá wọlé ni a gbé gún wọn lọ́wọ́ (Àrẹ̀mú 2009: 50; Adékọ́lá 2018). Èrò kúkúrú tí wọ́n ní nígbà náà ni pé, obìnrin kò lè kájú ìwọn nídìí iṣẹ́ ọ̀hún. Èró yìí wá ni Olúmúyíwá fi ṣẹ̀fẹ̀ nínú ìwé ìtàn àròsọ rẹ̀ *Oorun orí kẹ̀kẹ́*. A rí i kà pé Ìpínlẹ̀ Ayénígba nílò Kọ́míṣọ́nà ọlọ́pàá ní yàjóyàjó láti bá wọn dẹ́rọ̀ ìwà ọ̀daràn tó ń fojoojúmọ̀ gogò ní ìlú náà. Àìmọye Kọmíṣọ́nà ọlọ́pàákùnrin ni wọ́n sì ti gbé lọ síbẹ̀ àmọ́ tó jẹ́ pé, pàbó ni

gbogbo ìgbìyànjú wọn ń já sí. Èyí ló wá mú Ìnsìpẹ́kítọ̀ Àgbà gbé Kọmíṣọ̀nà tuntun to jẹ̀ obìnrin (ṣùgbọ́n tí ó rí i pé ó dáńtọ́) lọ síbẹ̀. Ọ̀rọ̀ yìí dá ọ̀pọ̀lọpọ̀ rúgúdù sílẹ̀ pàápàa láti ọ̀dọ̀ Gómìnà àti Ọba ìlú náà nítorí wọ́n wòye pé, ṣe ohun tí o mu ọlọ́pàákùnrin lómi ni apá ọlọ́pàákùnrin yóò wá ká. Gómìnà fi ìbínú sọ pe:

Lóbìnrin lásánlàsàn! Ṣé àwọn adigunjalè tọ́wọ́ ọkùnrin ò ká lọwọ́ obìnrin yóò ràn! (*Oorun orí kẹ̀kẹ́*: 21)

Kódà, nígbà tí Ìnsìpẹ́kítọ̀ Àgbà tilẹ̀ ń gbìyànjú láti ṣàlàyé fún un, ńṣe ló gbanájẹ tó wí pe:

Ọ̀gá ọlọ́pàá àgbà, obìnrin ni obìnrin yóò máa jẹ́ láéláé… Tiyín lẹ sọ yẹn o. Èmi ni aláàbò àgbà ní ìpínlẹ̀ yìí. Mi ò fẹ́ atẹ̀yìntọ̀ ní Kọmíṣọ̀nà ọlọ́pàá. (*Oorun orí kẹ̀kẹ́*: 22)

Nígbà tó tilẹ̀ yá, Ààrẹ ló pè tàárà láti fẹjọ́ sùn. Ó ní:

Ṣé ó wá yẹ kí ó ṣe àwà ni ọ̀gá ọlọ́pàá àgbà máa wá fún ní Kọmíṣọ̀nà ọlọ́pàábìnrin? Láwa tó ṣe pé wọ́n ń fi ojoojúmọ́ dojúkọ? *(Oorun orí kẹ̀kẹ́:* 22)

Sí ìyàlẹ́nu rẹ̀, ńṣe ni Ààrẹ̀ pàápàá tún pè é níjà nínú àlàyé rẹ̀. Ààrẹ ni:

Kí ló burú nínú ẹ̀ jare gómìnà wa? Ṣé ìwọ ò yan àwọn òbìnrin nínú Kọmíṣọ̀nà ni? (*Oorun orí kẹ̀kẹ́*: 23)

Lọ́gán ni Gómìnà fohùn akọ dáhùn pé:

Aàrẹ, ọ̀rọ̀ náà ò jọra o. Dùndún yàtọ̀ sí dùǹdún… Ọ̀rọ̀ ààbò ni eléyìí o.' (*Oorun orí kẹ̀kẹ́:* 23)

Lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ náà ni Ààrẹ̀ sì pa ọ̀rọ̀ náà mọ pẹ̀lú èsì tó mọ́gbọ́n wá pé:

Ṣé o mọ̀ pé àwọn ọlọpàá obìnrin lọ́gbọ́n lórí ju ọkùnrin lọ. O ò ṣe jẹ́ ká fi àwọn ọlọ́pàá sílẹ̀ kí wọ́n ṣiṣẹ́ wọn. Ọ̀gá àgbà ọlọ́pàá mọ ohun tí ó tọ́ láti ṣe. Ìyẹn ọ̀kan. Àtọjọ́ tí ẹ ti ń ní Kọmíṣọ̀nà ọkùnrin, kí ni wọ́n ṣe? *(Oorun orí kẹ̀kẹ́:*23)

Ó wá yẹ ká fi ojú sùnnùkùn wo èsì Ààrẹ yìí pé, ńṣe ni òǹkọ̀wé ń fọgbọ́n pe àkíyèsí pé ó ti tó àsìkò láti gba àwọn ọlọ́pàábìnrin náà láyé láti di ipò tó lóòrìn

mú nídìí iṣẹ́ ọlọ́pàá nígbà tó fẹ́ dàbí ẹni pé àwọn ọlọ́pàákùnrin kò fi gbogbo ara ta bíọ́bíọ́ mọ́. Ṣùgbọ́n, ó ṣe ni láàánú pe Oju òdìkeji ni àwùjọ fi wo ọrọ̀ náà pé obìnrin 'atẹ̀yìntọ̀ lásánlásàn' kò ní arà kankan tí wọ́n lè dá. Nítorí náà, kò yanilẹnu pé, orìṣiríṣi ìbéèrè ìsọnu ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí í ni bi Kọmíṣọ́nà Ìdòwú àti àwọn ọlọ́pàábìnrin tó kó sòdí wá. Irú ìbéèrè bẹ́ẹ̀ ni a rí tí ọ̀kan nínú akọ̀ròyìn bi í níbi ayẹyẹ ìkínni káábọ̀ rẹ̀ pé:

Ṣé ẹ̀rù ò bà yín nígbà tí ẹ gbọ́ pé Ìpínlẹ̀ Ayénígba ni ẹ̀ ń bọ̀?. *(Oorun orí kẹ̀kẹ́:*34)

Pẹ̀lú ìgboya to nípọn ni Kọmíṣọ́nà náà sì fi dáhùn pé:

Ẹ̀rù kẹ̀? Èmi gan ẹ̀rù…ẹ̀rù ò bà mí rárá. Àyà ò fò mí. Ẹ̀rù kì í bodò. *(Oorun orí kẹ̀kẹ́:*34)

Ní àwùjọ àwọn ọ̀daran pàápàá, ojú tìkàtẹ̀gbin ni wọ́n fi ń wo Kọmíṣọ́nà Ìdòwú àti àwọn ọlọ́pàábìnrin rẹ̀. Wọ́n kà á kún pé tí a bá tilẹ̀ sọ pé ẹranko oníwo ni yóò kan énìyàn pa pé, ṣe bí i ti ìmọ̀ran ìgbín ha ni. Èyí ló mú kí Dokita Kọ́lá, olórí fún àwọn ọ̀daràn ní ìlú náà bínú nígbà tí wọ́n ń ròyìn fún un bí ọ̀kan nínú àwọn ọlọ́pàábìnrin náà ṣe gbá ọ̀kan nínú àwọn ọ̀daràn náà létí. Pẹ̀lú ìbínú ni ó fi wí pé:

Àwọn obìnrin lásánlàsàn ló gbá Ṣọṣọ lójú yìí o. *(Oorun orí kẹ̀kẹ́:74)*

Ọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí túmọ̀ sí pé, kì í ṣe pé wọ́n gbá Ṣọṣọ lojú gan-an ni kókó bí kò ṣe pé 'obìnrin' ló gbá a. Nínú àjọ ọlọ́pàá gan-an ṣáájú ọ̀rọ̀ ti Kọmíṣọ́nà Ìdòwú yìí, bákan náà ni ọmọ ṣe orí. Wọn kò fi gbogbo ara ní ìgbẹ́kẹ̀lé kankan daindain nínú ọlọ́pàábìnrin. Bí ó ti lè wù kí ipò wọn ga tó, wọn kì í jẹ́ kí wọn ṣiṣẹ́ tayọ ọ́fíísì Ìǹsìpẹ́kítọ̀ Àgbà. Òǹkọ̀wé fi ìdí èyí múlẹ̀ nígbà tí ó wí pé:

Tẹ́lẹ̀, ọ́ọ́fíísì ọ̀gá ọlọ́pàá yányán fún àwọn ọlọ́pàá nìkan ni àwọn Kọmíṣọ́nà ọlọ́pàábìnrin ti máa ń ṣiṣẹ́. *(Oorun orí kẹ̀kẹ́:*26)

Nítorí náà, ohun àrà ni ìṣíninípò Kọmíṣọ́nà Ìdòwú jẹ́. Èyí kò sì sé lórí pé, Ìǹsìpẹ́kítọ̀ Àgbà kò rí Kọmíṣọ́nà Ìdòwú gẹ́gẹ́ bí i 'ọlọ́pàábìnrin' lásán bí kò ṣe "ọlọ́pàá tó kúnjú ìwọ̀n". A sì rí i nígbẹ̀yìn pé, Kọmíṣọ́nà Idòwú àti ikọ̀ rẹ̀ kò dójú tì í látàri àṣeyọrí tí wọ́n ní ní ìpínlẹ̀ Ayénígba débi pé Gomìnà àti Ọba ibẹ̀ kò fẹ́ kí wọ́n lọ mọ́. Òǹkọ̀wé fi àṣírí èyí hàn wá nígbà tí ó wí pé:

Inú góminà àti ọba kò dùn nígbà tí wọn gbọ́ pé DIG Ìdòwú padà sí Àbújá. Wọ́n fẹ́ kọ̀wé ìhónú sí Àarẹ orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Lọ́yà tí wọ́n bẹ̀ lọ́wẹ̀ ló gbà

wọ́n ni ìmọ̀ràn pé ipò tuntun tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ gbé obìnrin náà sí kọjá ti ẹni tó ń ṣe Kọmíṣọ́nà ọlọ́pàá. *(Oorun orí kẹ̀kẹ́:119)*

Síwájú sí i nínú ìtàn àròsọ náà, Olúmúyíwá jẹ́ kó yé wa pè àwọn ọ̀gá ọlọ́pàákùnrin a tún máa fi ọrọ̀ ìbálòpọ̀ lọ àwọn ọlọ́pàábìnrin abẹ́ wọn bẹ́ẹ̀ ni, wọn a máa fi ìyà àìnídìí jẹ ọlọ́pàábìnrin yòówù tó bá kọ̀ fún wọn. Wọn a máa bá a débi kí wọ́n má fún irú ọlọ́pàá bẹ́ẹ̀ ní ìgbéga lásìkò tó bà yẹ. Fún àpẹẹrẹ, Kọmíṣọ́nà Idòwú fojú winá irú àwọn ìpènijà báyìí lẹ́yìn ikú ọkọ rẹ̀ nígbà tí òun pàápàá ṣì wà ní túúlẹ̀ ọlọ́pàá. Òǹkọwé ṣàfihan èyí nísàlẹ̀:

…àwọn ọkùnrin kò jẹ́ sajẹ́ńtì Ìdòwú gbádùn… àfi bí ẹni pé wọn ti ń retí kí ọkọ rẹ̀ kú ni…Àwọn ọ̀gá rẹ̀ lẹ́nu iṣẹ́ gan-an kò fun ní ìsinmi. Bí wọ́n ti ń fòró ẹ̀mí rẹ̀ tó, kò jẹ́ wọn ní 'hoo'. Wàhálà àwọn ọ̀gá náà pọ̀ débi pé ó fẹ́rẹ̀ kọ̀wé fi iṣẹ́ sílẹ̀. Àìgbà fún àwọn ọ̀gá yìí mú kí ó pẹ́ lórí ipò Sájẹ́ńtì…síbẹ, Sájẹ́ńtì Ìdòwú kò káàárẹ̀ lẹ́nu iṣẹ́. Ṣúúrù, ìfaradà àti ìjáfáfá lẹ́nu iṣẹ́ lọ ràn án lọ́wọ́ láti ní ìgbéga… *(Oorun orí kẹ̀kẹ́:*90)

Àwọn eré onítàn náà fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, òṣìṣẹ́ tó ṣe é fọkàn tán tó sì mọṣẹ́ dójú àmì nídìí iṣẹ́ ọlọ́pàá ni àwọn ọlọ́pàábìnrin jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ó ti farahàn lára ẹ̀dá ìtan Àbẹ̀ní nínú eré onítàn *Olúwa L'o Mẹjọ́ Dá* tí Ọlábímtán àti Fẹ̀róníkà nínú *Gbamúgbamù* tí Akíntókun jẹ́ òǹkọ̀wé rẹ̀. Àwọn méjèèjì yìí ta bíọbíọ́ lẹ́nú iṣẹ́ ti a gbé fún wọn. Fún àpẹẹrẹ, Fẹ̀róníkà rí i pé òun tọpinpin, òun sì rí ọ̀daràn Gbamúgbamù mú nínú *Gbamúgbamù* tí Àbẹ̀ní náà sì rí Àkànní tọpinpin nínú *Olúwa L'o Mẹjọ́ Dá*. Bákan náà ni Fẹ̀roníkà kojú ìpènijà fífi ìfẹ́kúfẹ̀ẹ́ lọni láti ọ̀dọ̀ ọgá rẹ̀. Ọ̀gá yìí kó mú-un ní kékeré rárá nígbà tí onítọ̀hún kọ̀ fún un; ó dúnkokò mọ́ ọn bẹ́ẹ̀ ló sì tún fi ìyà àìnídìí jẹ ẹ́ láìmọye ìgbà. Ó rí èyí ṣe ní ìrọ̀rùn nítorí Fẹ̀roníkà ṣèèṣì lóyún fún ọ̀daràn tí wọ́n ní kó ṣe ìwádìí rẹ̀, èyí tí kò sì bá òfin iṣẹ́ wọn mù. Ọgá yìí wà kàn-án nípa fún un pé kó lọ ṣẹ́ oyún náà ní wéréwéré kí ó sì kó wá sí ilé oùn gẹ́gẹ́ bí ìyàwó kẹrin bí bẹ́ẹ̀ kọ́, òun yóò yọ ọ́ níṣẹ́: A rí ìṣẹ̀lẹ̀ yìí hú yọ nísàlẹ̀ báyìí:

Ó dáa, kọ̀ndísàn méjì ni mo fẹ́ fún ọ. Tó o bá ti lè fùfíílì wọn, ìjà ti parí, kò séwu ìdàdúró fún ọ mọ́. Àmọ́ bí bẹ́ẹ̀ kọ́ Fẹ̀róníkà, (Ó dìde wùyà), mo ti gbé idà ìdájọ́ mi sókè, kò sì gbọdọ̀ wálẹ̀ lọ́wọ́ òfo.…
Yù síí! Mo fẹ́ kí o lọ hàbọ́ọ̀tì oyún yìí. Irú rẹ̀ kọ̀ ló yẹ kó lóyún fún ọ̀daràn. Kò ṣé é gbọ́ sétí. Ó yá lọ mú oyún náà kúrò. …
(Pẹ̀lú ohùn tó le díẹ̀)… kọ̀ndísàn kejì rèé (Ó ń fọwọ́ bù ú lára) Mo fẹ́ kí o kó wá sọ́dọ̀ mi kọ́sẹ̀ yìí tó parí…Bí o bá ti lè mú àwọn nǹkan wónyìí ṣẹ kò sí ìfòyà. Ìgbéga rẹ á sì máa yá kíakía. N ó sọ ẹ́ dolórí ọlọ́pàá obìnrin ní ẹ̀kùn yìí. O ó sì gbádùn mi tó…' *(Gbamúgbamù:*80-81)

Lóòótọ́ ni pé lílóyún fún ọ̀daràn lẹ́nu iṣẹ́ ìwádìí kò bófin iṣẹ́ ọlọ́pàá mù ṣùgbọ́n, ọ̀rọ̀ Fẹ̀rọ́níkà dàbí kíkojú Òkun Pupa níwàjú tí ogun Fáràò sì tún ń lé e bọ̀ lẹ́yìn. Ó ṣẹlẹ̀ pé, ọ̀daràn alàìláàánú abojúwonko ni Gbamúgbamù tí wọ́n ni kó lọ tọpinpin nítorí náà, kí ọ̀rọ̀ rẹ̀ má bà à mú ìfura dání, ó ní láti díbọ́n fún Gbamúgbamù gẹ́gẹ́ bí i ọ̀dọ́mọ̀bìnrin kékeré kan tó ṣẹ̀ṣẹ̀ jáde ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga tó sì ń wáṣẹ́ ní yàjóyàjó tó sì tipa bẹ́ẹ̀ di 'olólùfẹ́' rẹ̀. Èyí ló wá kàn án nípa fún Fẹ̀rọ́níkà láti ṣe bí olólùfẹ́ délẹ̀délẹ̀ fún Gbamúgbamù nítorí, ó mọ̀ pé tí awó bá ya, ikú ni. Bí oyún sì ṣe wọlé wẹ́rẹ́ nìyíì. Ó wá ṣeni láàánú pé ṣáájú àsìkò yií, ńṣe ni àwọn ọkùnrin kàn ń gbé Fẹ̀rọ́níkà ní àgbéjùsílẹ̀ nítorí kò lóyún ààrọ̀ dalẹ́ rí, èyí ló wá mú un kọ̀ láti ṣẹ́ oyún ọ̀jiji yìí. Gbogbo ìtàn ara rẹ̀ yìí ló sì ń fi tó ọ̀gá rẹ̀ létí bí ó ti ń lọ kí ọ̀gá ọ̀hún tó wá padà dà á pẹ̀lú gbogbo ẹ̀bẹ̀ tí onítọ̀hún tún bẹ̀ ẹ́. Ní ṣọ́kí, ní ìpàdé àwọn lọgàálọ́gàá, ọ̀gá yìí wá irọ̀ bàǹtàbanta kan pa mọ́ ọn, ó tún tú àṣíri oyún ọ̀ràn tó ní. Báyìí ló ṣe jẹ́ pé ẹyẹ-kò-sọkà ni wọn yọ ọ́ níṣẹ́ láìfún un ní ẹ̀tọ́ kankan, (*Gbamúgbamù:* 84). Lẹ́yìn àìmọye ọdún tó ti jìyàjìṣẹ́ ni àṣírí ọ̀rọ̀ ṣẹ̀ṣẹ wá fojú hàn tí wọ́n sì gbà á padà.

Tí a bá wo gbogbo àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ òkè yìí, à ó rí i pé nítorí àwọn ọlọ́pàá yìí jẹ́ obìnrin ni gbogbo ẹ̀gbin yìí ṣe ta lé wọn. Tí kì í bá sì ṣe pé àwọn náà tẹpá mọṣẹ́, ní ìfaradà àti sùúru, tí wọ́n sì fàyàránṣoro ni, wọn ìbá máafi wọ́n pàtàn nídìí iṣẹ́ ọlọ́pàá ni. Irú ìhà tí àwọn ọlọ́pàábìnrin yìí kọ sí iṣẹ́ wọn ló mú Sydney-Agbor àti àwọn tókù rẹ̀ (2013) sọ pé:

> *'A number of studies on police attitude towards ethical issues ... have reported that female officers on the average expressed higher ethical standard than the male'* (2013: 338).
> Awọn iṣẹ́ ìwádìí kan lórí ìhà tí àwọn ọlọ́pàá kọ sí títẹ̀lé àwọn òfin tó de iṣẹ́ wọn fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn obìnrin ta bíọbíọ ju àwọn ọkùnrin lọ.

A lè sọ pé àwọn òǹkọ̀wé ìwé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ òkè yìí látara àwọn ẹ̀dá ìtàn àwọn ọlọ́pàábìnrin òkè yìí ń fihàn pé ohun ti a lérò pé ọkùnrin nìkan ló le ṣe, pé obìnrin pàápàá lè ṣe é, kódà, kó tún ṣe é tayọ. Olúmúyíwá fìdí èyí múlẹ̀ nínú ìtàn àròsọ rẹ̀ *Oorun orí kẹ̀kẹ́* nígbà tí ó wí pé:

> Ṣé o ò mọ̀ pé àwọn obìnrin lọ́gbọ́n lórí jú ọkùnrin lọ ni…Àtojọ́ tí ẹ ti ń ní kọmíṣọ́nà ọkùnrin, kí ni wọ́n ṣe? (*Oorun orí kẹ̀kẹ́*: 23)

Nítorí ìdí èyí, ìpè wà fún fífún àwọn ọlọ́pàábìnrin náà láàfààní láti ta bíọ́bió bí i ti àwọn akẹgbẹ́ wọn tí àjọ ọlọ́pàá bá fẹ́ túbọ̀ gòkè àgbà.

## 4.2 Àìní Ìlapa Ètò Òun Irinṣẹ́ Tó Mú Yányán

Ìpènijà mìíràn tí àjọ ọlọ́pàá tún ń kojú ni àìní ìlapa ètò òun irinṣẹ́ tó mú yányán. Fún àpẹẹrẹ, wọn kò ní àwọn irinṣẹ́ òun ohun èlò ìbára-ẹni-sọrọ̀ tó bágbàmu mọ́, àwọn ohun ìrìnsẹ̀ wọn ti dógùn-ún, àwọn òṣìṣẹ́ wọn kò tó àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ. Nínú ìwé ìtàn àròsọ *Oorun orí kẹ̀kẹ́*, Kọmiṣọ́nà Ìdòwú ló kọ́kọ́ pe àkíyèsí wa sí èyí nígbà tí ó wí pé:

> Àwọn ìbọ̀n àti àwọn àwọn ohun ìjà yín yòókù kò bóde mu mọ́. Bákan náà, aṣọ àti bàtà púpọ̀ nínú yín ló yẹ kí ìjọba ti pààrọ̀. *(Oorun orí kẹ̀kẹ́:*37)

Bẹ́ẹ̀ náà ni ọmọ ṣe orí nínú eré-onítàn Ìṣọ̀lá ìyẹn, *Ayé yẹ wọ́n tán.* A rí i pé ńṣe ni àwọn ọlọ́pàá ń mú kóńdó lásán ń lọ kojú àwọn ọ̀daran tó gbé ìbọn ìgbàlódé wá, à kò lè ṣẹ̀ṣẹ̀ máa sọ pé ọ̀hún kò dára, ńṣe ni àwọn ọlọ́pàá ọ̀hún na pápá bora gbẹ́yìn ni, (59). Nígbà tí ọ̀kan nínú àwọn akẹgbẹ́ wọn sì bèèrè ìdi tí wọn fi hu irú "ìwà ojo" bẹ́ẹ̀, lọ́gán ni wọ́n sì yára fún un lèsì pé: "Ní àwọn tó gbé ìbọn lọ́wọ́! Oníkóńdó àti Oníbọn?" (*Ayé Yẹ Wọ́n Tán:*80).

Ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn tó tún fìdí ìpènijà yìí múlẹ̀ la tún hú jáde nínú eré-onítàn *Ọlọ́run ò màwàdà*. Nínú rẹ̀, a rí i pé Sájẹ́ńtì Alábẹ̀dé àti àwọn ikọ̀ rẹ̀ kùnà láti mú àwọn olè tí wọ́n lọ kojú nítorí pé àwọn irinṣẹ́ tí wọ́n kò lọ kò lè dúró lẹ́gbẹ̀ẹ́ ti àwọn ọ̀daràn yìí rárá. Èyí tó wà pabambarì níbẹ̀ ni pé, ọkọ̀ tí wọ́n gbé lọ kò gbádùn rárá, ńṣe ló déédé dákú nígbà tí ìdojúkọ pẹ̀lú àwọn olè yìí ń lọ lọ́wọ́ nítorí ìdí èyí, wọn kò ráyè sá nígbà tí ojú ogun le. Nígbẹ̀yìn, ńṣe ni àwọn olè ọ̀hun rá àwọn ọlọ́pàá kó, tí wọ́n dè wọ́n lókùn bárábárá tí wọ́n sì lọ gbé wọn jù sí àgọ́ wọn pẹ̀lú onírúurú ìhàlẹ̀ pé wọn kò tún gbọ́dọ̀ yájú sáwọn mọ́! *(Ọlọ́run ò Màwàdà:* 22). A kò lè ṣẹ̀ṣẹ̀ ma sọ pé, ojú gba àwọn ọlọ́pàá ọ̀hún tì.

Ohun mìíràn tó tún farahàn nínú *Ayé Yẹ Wọ́n Tán* ni pé àìsí òṣìṣẹ́ tó ló mú kó jẹ́ pé, àjọ ọlọ́pàá kò rí ju ọlọ́pàá méjì péré mú silẹ̀ láti lọ pèsè ààbò ní gbọ̀ngàn àpèjẹ tí wọ́n pè fún Ọba Alayé àti àwọn ènìyàn pàtàkì ìlú Ìpo. Nígbà tí wọn yóò tún ba gbogbo rẹ̀ jẹ́, póńpó lásán ni wọ́n kó lé wọn lọ́wọ́. Nítorí nàà, kò fi gbogbo ara yanilẹ́nu pé nígbà tí àwọn ará ìlú tó wà fi ẹ̀hónú hàn dé, tí gbogbo rẹ̀ sì fẹjú tán, pé apá wọn kò ká a. Èyí ni òǹkọ̀wé yàwòrán rẹ̀ pé:

> 'Wọ́n rá gììrìgì síwájú, wọ́n ti àwọn ọlọ́pàá kúrò lọ́nà. Apá àwọn ọlọ́pàá kò ká wọn. Kóńdó àwọn ọlọ́pàá kò ran àdá àti kùmọ̀ tí àwọn ènìyàn mú lọ́wọ́' *(Ayé Yẹ Wọ́n Tán:*91).

Tí a bá wò ó, gbogbo àwọn ìpènijà yìí pẹ̀lú àwọn adígbọ̀nnákú tó ń dí àwọn ọlọ́pàá lọ́wọ́ láti ṣàṣeyè, èyí tó sì wá ń jẹ́ kí ṣiṣẹ́ṣiṣẹ́ wọn dàbí ọ̀lẹ. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn ìpènijà yìí tún jẹ́ okùnfà ikú òjijì lẹ́nu iṣẹ́ fún àìmọye àwọn ọlọ́pàá nígbà

tí wọn kò bá rí ǹǹkan tọ́jú tàbí, dáàbò bo ara wọn. Láti yanjú àwọn ìpènijà yìí, Ògúnníran nínú *Ọlọ́run ò màwàdà* sọ pé:

> 'Ìjọba tí yóò lo ọlọ́pàá bí irú èyí, gbọ́dọ̀ kọ́ dáábò bo ẹ̀mí ọlọ́pàá náà nípa fífún un lóhun èlò tó tayọ èyí táwọn adigunjalè kó wá' (*Ọlọ́run ò Màwàdà*:23).

## 4.3 Àìsí Ètò Amáyédẹrùn Tó

Adígbọnnàkú kan tún ni èyí fún àwọ́n ọlọ́pàá wa. Onírúurú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ láti inú àwọn àṣàyàn lítíréṣọ̀ wa fìdí èyí múlẹ̀. Àpẹẹrẹ irú ìpènijà yìí ni owó oṣù táṣọ́rẹ́, àwọn ilànà iṣẹ́ tí kò bá ara rẹ́, owó ìṣàkóso tí kò tó ǹǹkan, ilégbèé tí kò wuyì, fífúnni ní àwọn iṣẹ́ tí ń bu ìyì ẹni kù ṣe àti kíkọtí ikún àwọn aláṣẹ àjọ ọlọ́pàá sí ẹ̀dùn ọkàn àwọn òṣìṣẹ́ wọn. Lórí ti owó oṣù tàṣọrẹ́ fún àpẹẹrẹ, Adéyẹmí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ nínú *Ọ̀dájú ni wọ́n* nígbà tí ó wí pé: "…lóòótọ́, owó tí àwọn ọlọ́pàá ń gbà kò tó nǹkan, owó táṣọ́rẹ́ ni." (*Ọ̀dájú ni wọ́n:*10).

A ṣàkíyèsí pé, ìgbà mìíràn máa ń wà tí ara máa kó àwọn ọlọ́pàá tìọ̀ látí hùwà kò tọ́ ṣùgbọ́n tó ṣe pé ìpènijà òkè yìí ni kìí jẹ́. A rí èyí nínú ìwé ìtàn àròsọ *Oorun orí kẹ̀kẹ́* níbi tí ògbójú adigunjalè, ìyẹn Màràdónà, tí ń bú àwọn ọlọ́pàá pé òbìlẹ̀jẹ́ ni wọ́n ṣùgbọ́n ti akẹgbẹ́ rẹ̀ kan, ìyẹn Alábẹ́rẹ́, yára dáhùn pé:

> Ṣùgbọ́n bí a bá wò ó Màràdó, wọn ò lẹ́bi. Èló ni ìjọba ń san fún wọn?. Owó oṣù wọn kéré púpọ̀.*(Oorun orí kẹ̀kẹ́:*106).

> Èyí kín ọ̀rọ̀ (Àrẹ̀mú 2009: 66; 2017:24) lẹ́yìn nígbà tí ó wòye pé, owó oṣù táṣọ́rẹ́ tí àwọn ọlọ́pàá ń gbà nàá kúǹ àwọn òkùnfà tó ń mú wọn hùwà ìbàjẹ́ lẹ́nu iṣẹ́ wọn. Láti yanjú ìpénijà ọ̀hún, Olúmúyíwá nínú *Oorun orí kẹ̀kẹ́* dàbàá pé, ìpèsè aṣọ́ iṣẹ́, òṣìṣẹ́ àti owó tó tó fún ìṣàkoso àjọ ọ̀hún gbọ́dọ̀ wà. Ní àfikún, ó ní a gbọ́dọ̀ máa fún wọn ní ọ̀rọ̀ ìṣítí tí yóò máa mú orí wọn yá ní gbogbo ìgbà *(Oorun orí kẹ̀kẹ́:*36, 37).

Èyí tó tún kún àwọn ìpènijà òkè yìí ni tí àwọn ìlànà òun àbùdá tó de iṣẹ́ wọn ṣùgbọ́n tí kò bá ara rẹ́, tó sì ń fa ìrẹ̀wẹ̀sì fún wọn lẹ́nu iṣẹ́. Fún àpẹẹrẹ, àwọn ọlọ́pàá fúnrawọn rí iṣẹ́ wọn gẹ́gẹ́ bí èyí tó léwu tó sì tún ń gba àsìkò jù. Àrídájú kókó yìí ni a hú jáde nínú èrò Ìǹsìpẹ́kítọ Kọ́lá nígbà tó ń ro àròkan lórí ọ̀rọ̀ ìgbésí ayé rẹ̀ pé:

> Èwo ni kò tó rò nínú ọ̀rọ̀ mi? Ṣé ti iṣẹ́ ikú tí mò ń ṣe ni ká sọ ni tàbí gbígbé tí wọn ń gbé mi kiri? … Ṣé ká sọ pé n kò tí ì tó aya ní tàbí ká sọ pé n kò rí? Kì í kúkú ṣe pé n kò rí obìnrin tí mo fẹ́ fẹ́ ṣùgbọ́n, iṣẹ́ yìí ni kì í jẹ́ ki n ráyè párí ètò igbéyàwo. (*Oyin inú Àpáta:* 1).

A wòye pé kí ọlọ́pàá kan tó dé ipò Ìnsìpẹ́kítọ, ó ní láti bàlágà rékọjá àlà tí ó sì wá jẹ́ pé nínú àròkan rẹ̀ lókè yìí, kòì tí ì fẹ́yàwó nítorí kò rí ààyè, iṣẹ́ rẹ̀ ti gba gbogbo àsikò rẹ̀ tán. Ràbàràbà èyí ni pé, inú rẹ̀ kò dùn sí ara rẹ̀ àti iṣẹ́ náà. Ìbéérè wá ni pe, báwo ni orí yóò ṣe yá òṣìṣẹ́ tó wà nínú ipò yìí lẹnú iṣẹ́ débi tí yóò fi ri ohun mèremère gbé ṣe?

Àìsí ètò amáyédẹrùn tó fún àwọn ọlọ́pàá yìí náà tún jẹ yọ nínú ìgbéayé Òbíladé nínú *Ayé yẹ wọn tán*. Fún àpẹẹrẹ, nígbà tí ẹ̀gbọ́n rẹ̀ ń kí i káàbọ̀ láti ẹnu iṣẹ́, Òbíladé dáhùn pé:

‘Àwà nìyẹn, iṣẹ́ la rí’. *(Ayé Yẹ Wọn Tán*:22)

Ekukáká ni Òbíladé pẹ̀lú ọmọ rẹ̀ kanṣoṣo fi ń róúnjẹ jẹ. Ìgbà kan tilẹ̀ wà tó ṣe pé, o ní láti fi owó tó fẹ́ fi raṣọ ilé-ẹ̀kọ fún ọmọ ọ̀hún jẹun ni. Ó fi èyí hàn nígbà tí ó wí pé:

Ara owó tí mo fẹ́ fún Jọláadé ni mo kó kalẹ̀ un o. Owó aṣọ ilé-ìwé tó fẹ́ẹ̀ rà. *(Ayé Yẹ Wọn Tán:*22)

Irú ìgbéayé yìí ló sì sún un débi gbígba rìbá ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀rin náírà lọ́wọ́ Oyinadé, ògbójú fàyàwọ́ kan. A rí ìdí èyí nígbà tó ń ro àròkàn pé:

Ó fi ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀rin náírà gbún mi lọ́wọ́ kí n máa pin kiri… owó yìí yóò sì jọ àwa lójú nígbà tí a ò níkan tì. Iṣẹ tí í múni jẹun ọtá ẹni. *(Ayé Yẹ Wọn Tán:*33).

Àròkàn Òbíladé yìí ló wá jẹ́ ká ri i fà yọ pé nígbà mìírán, ara a máa ti àwọn ọlọ́pàá náà láti gbà tàbí bèèrè fún rìbá ṣùgbọn nitori pé gbogbo bí ǹǹkan kò ṣe ṣarajọ́ tó fún wọn nidií iṣẹ́ ọ̀hún wa lara ohun tó ń sún wọn débẹ̀. Pé Oyinadé tilẹ̀ tún wá fi owó rìbá ọ̀hún gún un lọ́wọ́ tún bà á nínú jẹ́ gidigidi. Nigbà tí ìjọba yóò tún túbọ̀ fọ́ gbogbo rẹ̀ pọ̀, wọn kì i tún san ìwọ̀nbá owó yìí lásìkò. A rí èyí dì mú nínú ọ̀rọ̀ Fẹ̀rọníkà, ọ̀kan lára àwọn ọlọ́pàábìnrin nínú *Gbamúgbamù*. Lẹ́yìn tí ìjọba ti jẹ àwọn ọlọ́pàá ni owó oṣù mẹ́jọ, wọn rápálá san mẹta péré nínú rẹ̀, èyí ló sì bí Fẹ̀rọníkà nínú tó fi figbe ta pé:

**Fẹ̀róníkà:** Owó oṣù méta kẹ̀! Nínú mẹ́jọ!! Ara nǹkan tíjọba wa ń ṣe tí ò tọ́ rè é o. Kín ni wọ́n fẹ́ ká máa jẹ? À ń ṣiṣẹ́ bí akúra, à ń jẹ̀jẹ ẹ̀lírí. (*Gbamúgbamù*: 57)

Kò sí òṣìṣẹ́ tó máa gbọ́ irú èyí tí ìrẹ̀wẹ̀sì ọkàn kò ní bá a. Ràlẹ̀rálẹ̀ irú ìpèníjà báyìí sì ni pé, ó ṣéeṣe kí ara irú òṣìṣẹ́ bẹ́ẹ̀ má yá síṣẹ́ mọ́ tàbí kó máa ṣe

màgòmágó lẹ́nu iṣẹ́. Èyí ni ọ̀gá ọlọ́pàá kan nínú ìwé ọ̀hun fi lélẹ̀ nígbà tí ó wí pé:

***'Ọ̀gá:*** Ìgbà tó bá yá, wọn á lolopaa ń gbowó ẹ̀yìn, wọn ń ṣọwọ́ kúdúrú. Ebi ò sì màwàdà'. (*Gbamúgbamù*:57)

Nítorí náà, kò fi gbogbo ara yanilẹ́nu nígbà tí ọlọ́pàá mìíràn nínú *Oyíndàmọ̀lá ọmọ ọlọ́rọ̀* ṣáfọ̀mọ́ rẹ̀ pé ọ̀pọ̀ àwọn ọlọ́pàá ni ọpọlọ wọn mú yányán, tí wọ́n mọ iṣẹ́ dójú àmì tí wọ́n sì lè ṣiṣẹ́ takuntakun ṣùgbọ́n tí wọ́n lè mọ̀ọ́mọ̀ ya ìmẹ́lẹ́ lẹnú iṣẹ́ fún ìdí kan tàbí òmíràn. Ọlọ́pàá náà sàlàyé pe:

> **Ọlọ́pàá kẹta:** Àwọn wọ̀nyìí rò pé àwọn gbọ́n lójú ara wọn ni o. Wọn kò mọ̀ pé ẹnìkan tún gbọ́n ju àwọn lọ. Ọgbọ́n tí ó wà nínú àwa ọlọ́paá ju ti ẹ̀yin ọ̀daràn lọ. Àfi bí a kò bá tí ì ṣetán láti mú un yín ló kù. (118)

Àlàyé òkè yìí bá òwe Yorùbá tó wí pé "Ọ̀bọ gbọ́n, tinú ọ̀bọ lọ̀bọ ń ṣe" mu. Eyí jẹ́ kò hàn yàǹyàyanya pé ọpọ̀ àwọn ọlọ́pàá la kọ́ dójú àmì tí wọ́n sì lè ṣiṣẹ wọn bí iṣẹ́ ṣùgbọ́n tó ṣe pé wọn á mọ̀ọ́mọ̀ ya ọ̀lẹ kalẹ̀.

Ìpò ẹdun arinlẹ̀ tí ọ̀pọ̀ nínú àwọn ọlọ́pàá wà yìí tún farahàn síwájú sí i nínú ìgbésí ayé Òbíladé. A rí i pé kì í ṣe pé ó ń ṣiṣẹ́ erin jẹ ìjẹ ẹ̀lírí nìkan ṣùgbọ́n pé, àwọn ọ̀nà gbogbo tí ó yẹ kó tún ti lè rí ìrànlọ́wọ́ owó ló tún di dídí pa láti ọwọ́ àwùjọ àti ìjọba fúnra rẹ̀. Fún àpẹẹrẹ, nígbà tí ọ̀dá owó dá a, tí ẹ̀gbọ́n rẹ̀ Àyánlọlá sì gbà á ní yànjú pé kó sáré wá owó ọ̀hún, pẹ̀lú ẹ̀dùn ọkàn tó ga ló fi dáhùn pé:

'Bí ibo? Gbogbo àwọn ọ̀rẹ́ wa tó lówó kò fẹ́ yáwa. Wọ́n ń bẹ̀rù bóyá a lè má tètè rí i san. Mo ha bá wọn wí? A dé báńkì, wọn ní ká lọ mú ìdúró wá. Kí ni mo fẹ́ fi dúró? Ẹsẹ̀ ọ̀hún da? N ò lẹ́sẹ̀… Èló ni mò ń gbà?' (*Ayé yẹ́ wọ́n tán:*29)

Kò sí ẹ̀dá kàn tó máa wà nínu irú ipò báyìí tí ayé kò ní fẹ́rẹ̀ẹ́ sú. Ràbọ̀ràbọ̀ ìpénija yìí tó ti di ọgbẹ́ ọkàn fún àwọn ọlọ́pàá náà ni a tún rí tí àwọn ọlọ́pàá inú *Ọlọ́run ò màwàdà* ń gbà bí ẹni ń gba igbá ọtí láàárín ara wọn báyìí nísàlẹ̀ pé:

**'Kọ́búrù Adéfilá:** Ẹ tilẹ̀ wo ìyà tí wọ́n fi ń jẹ wá. Tí kì í bá ṣe iṣẹ́ tí kò sí lóde, iṣẹ́ ọlọ́pàá kì í ṣe iṣẹ́ gidi. Iṣẹ́ ìyà gbáà ni. Èló ni wọ́n ń fún wa lóṣù?

**Sájẹ́ńtì Alábẹdé:** Owó ìdákọmu.

**Kọ́búrù Adéfilá*:*** Nínú rẹ̀ la ó ti ra tọ́ọ̀ṣì-laìtì àti bátìrì. Nínú rẹ̀ láá ti í wọkọ̀ àlọ àti àbọ̀ lọ síbikíbi tí wọ́n bá rán wa láti ṣiṣẹ́. Bí a bá dúró sangbọndan sínú òòrùn táìsàn kọlu ni, inú owó ọ̀hún làáti í ra òògùn… à ń ṣiṣẹ́ bí aago, a kò lọ síwájú bí aago… Iṣẹ́ la rí, a ò rówó, ẹ̀wù ò pé méjì lọ́rùn bẹ́ẹ̀ la à jẹun yó. A ò rówó tọ́jú aya àtọmọ. Báwo la ṣe fẹ́ kọ́lé láyé…' (*Ọlọ́run ò màwàdà:*2)

Yàtọ̀ sí gbogbo àwọn ìyà òkè yìí, a tún rí àwọn ilànà tàbí òfin iṣẹ́ àjọ ọlọ́pàá tí kò bá ara rẹ́ rárá. Lára rẹ̀ ni kí wọ́n máa fún àwọn òṣìṣẹ́ wọn ní àwọn ojúṣe tí kò pọ́n ènìyàn lé, tí kò buyì kúnni ṣe. Wọ́n lè sí wọn nípò lọ ilé àwọn olówó tàbí àwọn ọ̀tọ̀kùlú láwùjọ láti lọ máa ṣiṣẹ́ tí yóò fẹ́rẹ̀ fara pẹ́ iṣẹ́ ọmọ-ọ̀dọ̀, èyí a sì máa mú kí ara tì wọ́n. Sájẹ́ǹtì Alábẹdé ló ṣí aṣọ lójú èyí nínú *Ọlọ́run ò màwàdà* nígbà tí ó sọ pẹ̀lú ìrira pé:

**'Sájẹ́ǹtì Alábẹ*dé:***Àbùkù àti ìwọ̀sí tó rọ̀ mọ́ iṣẹ́ náà ló tilẹ̀ máa ń mẹ́kún gbọnni. Wọ́n lè ní kọlúwarẹ̀ máa lọ ṣọdẹ bí ọdẹ tàbí ṣọ́lé ọlọ́lá tàbí máa ṣílẹ̀kùn fáwọn ọmọ tí kò tó imí ìdí olúwa rẹ̀…' (*Ọlọ́run ò màwàdà:*2)

Lóòótọ̀ láìṣègbè sí apá kan, irú àwọn ojúṣe báyìí lè mú kí ara òṣìṣé máa lọ́ tìkọ̀, ki ara má sì yá gágá síṣẹ́. Láti wá fọ́ gbogbo rẹ̀ lójú pọ̀, ńṣe ló wạ dàbí pé àwọn aláṣẹ àjọ ọlọ́pàá ya elétí ikún àti afọ́jú tí kì í gbọ́ tàbí rí gbogbo ìpènijà àwọn ọlọ́pàá yìí, ó dàbí ẹni pé wọn kò tilẹ̀ mú ọ̀rọ̀ tó bá kan àwọn òṣìṣẹ́ wọn lọ́kúnkúndùn rárá. Ọ̀rọ̀ yìí ni Kọ́ństábù Kọ́lápọ̀ ń pe àkíyèsí Ìnsìpẹ́kítọ̀ Ìjàòdọlà sí nígbà tí onítọ̀hún ń ka gbogbo àwọn ìpènijà tí wọ́n ní fún Kọmíṣọ́nà Ọlọ́pàá titun tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ gbé dé. Kọ́ństábù Kọ́lápọ̀ ní:

**'Kọ̀ǹstebu Kọ́lápọ̀:** Ọ̀rọ̀ tẹ́ẹ̀ sọ dáa ọgá. Àfàìmọ̀ kó má jẹ́ ẹ́ pé ẹ̀yìn igbá lẹ̀ ń yíngbàdo si; a kò ṣẹ̀ṣẹ̀ máa wí i, etí ni wọ́n fi ń gbọ̀n ọ́n dànù' (*Ọlọ́run ò màwàdà:*40).

Ọ̀rọ̀ tí Kọ́ńtébù sọ lókè yìí ṣe kókó gán-an nítórí, àjọkájọ tó bá fẹ́ ní àṣeyọrí tàbí ìtẹ̀síwájú, tí kò fẹ́ kí ohun gbogbo fọ́pomọ́yọ̀ gbọ́dọ̀ máa tẹ́tí sí àròyé òun ẹ̀dùn ọkàn àwọn òṣìṣẹ́ rẹ̀ kí wọ́n sì máa gbé ìgbésẹ̀ akin lórí rẹ̀. Èyí ń tọ́ka pé, tí ìjọba tàbí àwọn aláṣẹ àjọ́ ọlọ́pàá kò bá gba ọ̀rọ̀ àwọn ọlọ́pàá yìí yẹ̀wò kí wọ́n sì mú kí ìgbéayé dẹ̀ wọ́n lọ́rùn, bí ìgbà tí wọ́n finá sorí òrùlé sùn ni nítórí bó pẹ́ bóyá, àwọn ọlọ́pàá náà yóò ṣìwàhù. Láfikún, àwọn àhesọ ọ̀rọ̀ kan ń jà rànyìn láwùjọ pé àwọn ọmọ gànfè, ọmọ ìsọta, ni iṣẹ́ ọlọ́pàá wà fún gẹ́gẹ́ bí Àrẹ̀mú pàápàá ti wòye (Àrẹ̀mú 2017:9). Ó sì ṣe ni láàánú pé, àwọn ọlọ́pàá mìíràn pàápàá ní irú èrò yìí gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ yọ nínú ìtàkúrọ̀sọ wọn nísàlẹ̀ yìí nínú *Ayé yẹ wọ́n tán*:

**'Ọlọ́pàá II:** Àìríṣẹ́ ló lé mi dé ìdí iṣẹ́ ọlọ́pàá. Bí mo bá ríṣẹ́ mò ń lọ**.**

**Ọlọ́pàá I:** Ìyẹn nipé iṣẹ́ ọlọ́pàá kì í ṣe iṣẹ́?

**Ọlọ́pàá II:** Iṣẹ́ ni. Ó kàn jẹ́ pé kì í ṣe iṣẹ́ ọmọlúàbí ni. Iṣẹ́ la rí ko sówó' *(Ayé yẹ wọ́n tán: 80).*

Ìtàkúrọ̀sọ wọn àti èrò Àrẹ̀mú lókè yìí fihàn pé tí a bá tilẹ̀ rí ẹnìkan tó wọnú iṣẹ́ ọlọ́pàá pẹ̀lú ọkàn mímọ́, nígbà tí yóò bá fi ya, ó ṣeéṣe kí òun náà a ti jingíri nínú ìwà ìbàjẹ́. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Sherma nínú Àrẹ̀mú (2014: 53) pé, ọ̀pọ̀ àwọn túúlẹ̀ ọlọ́pàá ló wọlé pẹ̀lú ọkàn mímọ́ ṣùgbọ́n tó ṣe pé nígbà tí wọn

yóò fi fẹ̀yìn tì lẹ́nu iṣẹ́ ọ̀hùn, ìwà ibàjẹ́ ti gogò sí wọn lára èyí to sì wá jẹ́ kó dàbí ẹni pé láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀, àìrikanṣekàn ló pilẹ̀ ń jẹ́ kí àwọn ènìyàn gba iṣẹ́ náà.

Ògúnníran nínú *Ọlọ́run ò màwàdà,* tẹnumọ́ ọ́n pé sísan owó oṣù tó tó àti ní àsìkò ló lè tán ìṣoro ìpènijà yìí. Ó ní:

‘Ọmọ tí kò yó yóò jalè. Bó bá ṣe ìjọba ni o, bó ṣe àwọn aláṣẹ tí ń darí iṣẹ́ ọlọ́pàá tàbí ti ààbò ìlú ni o: òwe tí mo pa nnì ni kí wọn gbe yẹ̀wò...láì jẹ́ bẹ́ẹ̀, kò sígbà tí wọn kò ní máa rẹ́ni yọ dànù nínú iṣẹ́ ọlọ́pàá’ (*Ọlọ́run ò màwàdà:*40).

## 5. Ìrú Ìjọba àtí Àwọn Olórí Ọlọ́pàá tó wà Lóde

A rí i fà yọ nínú àwọn ìwé àṣàyàn pé àjọ ọlọ́pàá náà pilẹ̀ ní àwọn ìṣòro lábẹ́lẹ̀ tó ń bá a fínra èyí tí a lè sọ wí pé àìní àwọn olórí tó dára ń ṣe òkùnfà. Fún àpẹẹrẹ, àwọn ìwé àṣàyàn yìí fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé a ní àwọn ọ̀gá ọlọ́pàá tí wọn kò kúnjú ìwọ̀n lẹ́nu iṣẹ́ mọ́. Òkédìjí fidí èyí múlẹ̀ nínú ìwé ìtàn àròsọ rẹ̀, *Àjà ló lẹrù* látara ẹ̀dá ìtàn Áúdù Kàrímù, ọ̀gá ọlọ́pàá. Ọ̀pọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ ló fi hàn pé ẹ̀dá ìtàn yìí kò tilẹ̀ ní àwòmọ́ kanṣo tí fi lè pè é ní olórí tàbí aṣíwàjú rere tó lè tukọ̀ àjọ ọlọ́pàá dé èbúté àṣeyọrí; kò ní àròjinlẹ̀, kò ní sùúrù, onífun kan bí i tejò ni, ìrònú rẹ̀ kúrú, kò rí kọjá imú rẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni gànràngànràn rẹ̀ pọ̀! Kò sì yani lẹ̀nu pé, gbogbo àwọn àwòmọ́ burúkú yìí ló fi yí àwọn òṣìṣẹ́ abẹ́ rẹ̀ lára débi pé, wọn kò dá ṣe àṣeyọrí iṣẹ́ kankan. Àwọn ibi tí wọ́n ti rí ọ̀daràn mú jẹ́ àwọn iṣẹ́ tí Lápàdé ti parí tó kàn mọ̀ọ́mọ̀ kẹ́ sílẹ̀ fún wọn. Yàtọ̀ sí èyí, gbólóhùn Yorùbá yìí pé “Bí orí bá ti bàjẹ́, gbogbo ẹ̀yà ara tó kú náà yóò díbàjẹ́” bá ìṣẹ̀lẹ̀ yìí mu. A ri hú jàde pé lọ́pọ̀ ìgbà tí àwọn ọlọ́pàá yìí bá ti dọ̀gá, wọ́n máa ń ya ọ̀lẹ kalẹ̀ ni. Ọ̀pọ̀ wọn a máa gba rìbá, wọn a máa dún mọ̀hurumọ̀huru mọ́ àwọn òṣìṣẹ́ abẹ́ wọn, wọn a máa lé àwọn ọlọ́pàábìnrin abẹ́ wọn káàkiri tàbí kí wọ́n ya ọ̀lẹ́dàrùn kalẹ̀. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ìjà olórogún tí kò wúlò ni wọn yóò máa bá ara wọn jà. *Ayé yẹ wọ́n tán* àti *Gbamúgbamù* fidí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọ̀pọ̀ ìgbà ló ṣe pé ńṣe ni àwọn ọ̀gá ọlọ́pàá yìí á ya ọ̀lẹ́dàrùn tí wọn yóò sì máa dọ́gbọ́n yẹ iṣẹ́ sílẹ̀ fún àwọn òṣìṣẹ́ abẹ́ wọn ni. Nínú *Ayé yẹ wọ́n tán* fún àpẹẹrẹ, ọ̀gá ọlọ́pàá kan pẹ̀lú àwọn ọlọ́pàá díẹ̀ lọ láti lọ dẹ́rọ̀ ìjàgboro kan tó ṣẹ̀lẹ̀ ṣùgbọn nígbà tí wọ́n dọ́hùn-ún, ńṣe ni ọ̀gá ta kété tó kàn ń fẹ̀fun pàṣẹ pé:

‘Ẹ dè wọ́n! Ẹ dè wọ́n!’ (58)

Bákan náà, nínú *Gbamúgbamù,* ńṣe ní kọmíṣọ́nà ọlọ́pàá kàn ń gbókèrè pàṣẹ ni tí òun fúnra rẹ̀ kò sì kó ipa kankan gúnmọ́. Èyí da ìrẹ̀wẹ̀sì sí wọn lọ́kàn débi tí ọ̀kan nínú wọn fi ìrira sọ̀rọ̀ pé:

**'Ọ̀gá ọlọ́pàá kejì:** (Ó mí kanlẹ̀) Hùn-ùn! Ẹni gbaṣẹ́ ọlọ́pàá gbà yọnu po o. Ìyàwó lóyún ọ̀nà ò gbọkọ wo wá lèyíí báyìí. Káwa lọ máa forí la igbó àwọn ọ̀daràn kiri, tóò!' (*Gbamúgbamù:*25)

A kò nílò láti ṣẹ̀ṣẹ̀ máa sọ pé òfo ọjọ́ kejì ọjà ni àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ òkè méjèèjì náà já sí. Ó wà dàbí ẹni pé ńṣe ni kọmiṣọ́nà Ìdòwú fẹ́ wá àtúnṣe sí irú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ báyìí ni to fi ń gba àwọn ọlọ́pàá abẹ́ rẹ̀ níyànjú nínú *Oorun orí kẹ̀kẹ́* pé tọ̀gátọmọṣẹ́ ló gbọ́dọ̀ pawọ́pọ̀ ṣiṣẹ́ kí àṣeyọrí tó lè wà. Ó ní:

'Èmi làgbà, èmi lọ̀gá lè ṣe àkóbá fún iṣẹ́ wa. Ẹ jẹ́ ká gbé ìyẹn tì.' *(Oorun orí kẹ̀kẹ́*: 43)

Títẹ̀lé àmọ̀ràn yìí sì jẹ́ lára ìdí kan gbòógì tí kọmiṣọ́nà náà àti ikọ̀ rẹ̀ fi ni àṣeyọrí rẹpẹtẹ. Kọmiṣọ́nà Ìdòwú kìí kàn kó àwọn ikọ̀ rẹ̀ lọ síta lásán ṣùgbọn, òun pàápàá á fi tọkàntara ṣiṣẹ́ ọ̀hún ni. Nítorí náà, kò fi gbogbo ara yanilẹ́nu pé àwọn òṣìṣẹ́ abẹ́ rẹ̀ náà mú irú àwọn àwòmọ́ yìí lára rẹ̀, àwọn náà a sì máa fi ṣiṣẹ́ wọn pẹ̀lú orí yíya.

Nígbà mìíràn, bí ara á ṣe máa yá àwọn ọlọ́pàá sí láti ṣiṣẹ́ ní í ṣe pẹ̀lú ìhà tí ìjọba tó wà lórí àléefà kọ sí gbígbọ́ búkátà àjọ ọlọ́pàá, ṣé owó ni kẹ̀kẹ́ ìhìnrere. Ààrùn ojú ni láti sọ pé àjọ ọlọ́pàá nílò owó rọ̀gbùnrọ́gbún láti mú wọn ṣe ojúṣe wọn ní àṣeyọrí gẹ́gẹ́ bí Àrẹ̀mú (2014; 2017) ṣe ṣàfọ̀mọ́ rẹ̀ pé:

"Effective policing depends on adequate budgetary allocation to the security of which the police are the primary agents" (Ìṣọ́ òun ààbò tó péye dá lé ìpèsè owó tó tówó fún ẹ̀kà tó wà fún ètò ààbò èyí tí àjọ ọlọ́pàá jẹ́ ọ̀kan.)

Àmọ́, ó ṣeni láàánú pé ọ̀pọ̀ gbogbo àwọn ìjọba tó ti gorí àléefà láti àìmọye ọdún sẹ́yìn ló ti fi owó jẹ àjọ ọlọ́pàá níyà, (Adékọ́lá: 2018). Adékọ́lá jẹ́rìísí èyí nígbà tó tọpinpin orísun ìpènijà yìí dé àsìkò tí a gba òmìnira lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ó ní nígbà náà, àwọn ọlọ́pàá tó ẹgbẹ̀rún mejílà; wọn pọ̀ ju àwọn sọjà ológun lọ bẹ́ẹ̀ ni ní àsìkò tí à ń sọ yìí, ìjọba ológun ló wà lórí àlèéfà. Èyí ló wà jẹ kí àwọn ológun rí wọn gẹ́gẹ́ bí ọ̀tá tí wọ́n sì ṣe tipa bẹ́ẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí ní fi owó jẹ àjọ náà níyà kí ọwọ́ wọn má ba a tórí, (Adékọ́lá: 2018). Fún ìdí èyí, kò gbọdọ̀ yanilẹ́nu pé ti ìjọba tó bá wà lórí àléefà bá ń kùnà láti pèsè owó tó tó fún àjọ ọlọ́pàá, wọn kò ní lè ṣe bó ṣe yẹ.

Àwọn ìwé àṣàyàn wa jẹ́rìí sí i pé lóòótọ́, ọ̀pọ àwọn ìjọba tó ti gorí àléefà kí í fi gbogbo ara gbọ́ bùkátà àwọn ọlọ́pàá gẹ́gẹ́ bí a ti fidí rẹ̀ múlẹ̀ lábẹ́ "àìní ìlapa ètò òun irinṣẹ́ tó mú yányán" lókè. Igbá-kejì ọgá ọlọ́pàá lórílẹ̀-èdè Nàìjíríà nígbà kan rí ìyẹn Chris Omeben, ṣàfọ̀mọ́ rẹ̀ yanyayanya pé nígbà kan rí, àwọn ológun a tilẹ̀ máa gba owó oṣù tó ju ti àwọn ọlọ́pàá lọ èyí tó wá jẹ́ kí àwọn ọlọ́pàá máa rí ara wọn gẹ́gẹ́ bí òṣìṣẹ́ tí kò níye lórí tó. Èyí ló mú un dábàá pé bóyá kí wọ́n kúkú máa jọ kọ́ wọn ní irú ẹ̀kọ́ kan náà, kí wọ́n sì tún

jọ máa gba irú oyè kan náà gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti ń ṣe ní àwọn orílẹ̀-èdè bí i Thailand and South Africa (Brownson 2012:73).

Yàtọ̀ sí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ òkè yìí, àwọn ìwé àṣàyàn wa tún fi kún un pé lọ́pọ̀ ìgbà, àwọn ìjọba tó bá wa lórí àlééfà (yálà alágbádá tàbí ológun) a máa sọ àwọn ọlọ́pàá di irinṣẹ́ ara wọn tí wọn yóò kàn máa lò fún àǹfààní tara wọn nìkan. Irú ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ni Ìṣọlá ń ṣàfihàn rẹ̀ nínú *Ayé yẹ wọ́n tán.* Ọba Simisọ́lá (tí ó ń dúro gẹ́gẹ́ bí ìjọba), ṣi ipò rẹ̀ lò gẹ́gẹ́ bí ọba alayé ilú Ìpo nípa pípàṣẹ fún ọ̀gá ọlọ́pàá àti ikọ̀ rẹ̀ láti lọ máa halẹ̀ mọ́ kí wọ́n sì ma kó àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Ẹgbẹ́ Alájùmọ̀ṣe (tí ó ń dúró fún àwọn ẹgbẹ́ olóṣèlú alátakò). Wọn a nà wọn bí ẹni ma kú, wọ́n á sì tún da ìpàdé wọn rú. Nígbà tí àwọn gìdìgáǹkó olóṣèlú dééde ń rá wọn kó, ńṣe ni àwọn ọlọ́pàá yára gbé ojú sẹ́gbẹ̀ẹ́, tí wọ́n ṣebí ẹni pé àwọn kò rí ohun tó ṣẹlẹ̀. (*Ayé yẹ wọ́n tán:* 56-58, 87).

Síwájú sí i, àwọn ìwé yìí túbọ̀ jẹ́ ká mọ̀ pé kì í ṣe pé àwọn ọ̀gá ọlọ́pàá ń hùwà ìbàjẹ́ nìkan àmọ́ pé, ṣe ni wọ́n tún fi ń kọ́ àwọn òṣìṣẹ́ abẹ́ wọn. Èyí ni àwọn ọ̀gá tí àwọn ènìyàn ti gbójú lé pé wọn yóò bá wọn ṣẹ́gun ìwà ìbàjẹ́ láwùjọ tó wá ṣe pé àwọn gan-an ni wọ́n ń gbé e lárugẹ, tí wọ́n tún wá ń ti àwọn òṣìṣẹ́ abẹ́ wọn sí i. Àpẹẹrẹ irú ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ni ti Ìǹsìpẹ́kítọ̀ Ìjàòdọlà tó ń fi ọgbọọgbọ́n kọ́ àwọn òṣìṣẹ́ abẹ́ rẹ̀ (ìyẹn Sájẹ́ńtì Alábẹdé àti Kọ́búrù Adéfilá) ní ìwà ìbàjẹ́ pé kí wọ́n lọ máa dúró nírònà láti ṣàyẹ̀wò ọkọ̀ lọ́nà tí kò bá òfin mu, (*Ọlọ́run ò màwàdà:* 3). Bákan náà, ọ̀gá Ìǹsìpẹ́kítọ̀ Ìjàòdọlà pàápàá, ìyẹn Kọmíṣọ́nà Ajẹunsínúdekú, náà kò gbẹ́yìn nínú irú ìwà ìbàjẹ́ yìí. Òun ló pàṣẹ fún Ìǹsìpẹ́kítọ̀ Ìjàòdọlà láti lọ da ojú ìwàdìí ẹjọ́ ìpànìyàn tí wọ́n ń ṣe lọ́wọ́ rú nípa gbígbé ẹ̀bi fún aláre, (*Ọlọ́run ò màwàdà:*61). Irú ìṣẹ̀lẹ̀ yìí náà ni a tún rí hú jáde nínú *Gbamúgbamù* níbi tó ṣe pé, owó rìbá tí ọlọ́pàá rí gbà bọ̀ láti oko ìwàdìí ni ọ̀gá ọlọ́pàá ń bèèrè fún lọ́wọ́ rẹ̀, kò tilẹ̀ bèèrè nípa àbọ̀ ìwádìí rárá, (*Gbamúgbamù:* 61). Nigbà tí onitọ̀hún si ṣàlàyé pé wọn kò fún òun ní owó kankan bẹ́ẹ̀ ni òun kò sì bèère, pẹ̀lú ìbínú ó fi sọ̀rọ̀ burukú sí i. Dájúdájú tí ó bá di ọjọ̀ mìíràn, irú ọlọpàá bẹ́ẹ̀ kò ní fẹ́ 'ṣánpá wálé'. Èyí túmọ̀ si pé, bí wọn kò tilẹ̀ fi lọ̀ ọ́, yóò gbà á ní tipátipá. Ní àfikún, àwọn ọ̀gá ọlọ́pàá mìíràn fẹ́ràn kí wọ́n máa fi ìlọ̀kulọ̀ lọ àwọn ọlọ́pàábìnrin tó jẹ́ òṣìṣẹ́ lábẹ́ wọn bẹ́ẹ̀ ni wọn a tún máa hàlẹ̀ mọ́ wọn. Gbogbo èyí là ṣàfihàn látara Fẹ̀rónìkà nínú *Gbamúgbamù* àti Kọmíṣọ́nà Ìdòwú nínú *Oorun orí kẹ̀kẹ́,* gẹ́gẹ́ bí a ti mẹ́nubà á lókè.

Ojútùú sí àwọn ìpènijà yìí ni pé ní àkọ́kọ́, àwọn aláṣẹ nínú àjọ ọlọ́pàá gbọ́dọ̀ rí i pé àwọn òṣìṣẹ́ tó jẹ́ ọmọlúàbí tó sì ṣe é fọkàn tán gẹ́gẹ́ bó ti farahàn lára Kọmíṣọ́nà Ìdòwú nínú *Oorun orí kẹ̀kẹ́* ni wọ́n gbé sí ipò àṣẹ. Lẹ́ẹ̀kejì, akitiyan gbọ́dọ̀ máa wà lóórèkóòrè láti máa fi gbogbo àwọn ìpènijà tí wọ́n bá ń kojú tó ìjọba létí yálà wọ́n gbọ́ tàbi, wọn kò gbọ́. A rí èyí kọ́ látara Ìǹsìpẹ́kítọ̀ Ìjàòdọlà nínú *Ọlọrun ò màwàdà,* tí kò káàárẹ̀ láti fi àwọn ìpènijà wọn tó Kọmíṣọ́nà tuntun létí bí ó tilẹ̀ ṣe jẹ́ pé ìgbà àkọ́kọ́ tí wọn yóò ṣe bẹ́ẹ̀ kọ́ nìyìí, (*Ọlọ́run ò màwàda:*40)

## 6. Ìwà òbìlẹ̀jẹ́ láàárín àwọn Ọlọ́pàá fúnra wọn

Ìpènijà ńlá ni èyí jẹ́ fún àjọ ọlọ́pàá. Bẹ̀ẹ̀rẹ̀ láti inú àwọn ìwé ìtàn àròsọ fún àpẹẹrẹ *Oyin inú àpáta,* òǹkọ̀wé (Ṣóẹ̀tán) ṣàfihàn bí Akilápá tó jẹ́ ọlọ́pàá ṣe tún jẹ́ agbódegbà fún àwọn ìgárá adigunjalè. A máa tú àwọn àṣírí ìjọba fún wọn, a sì máa kó ìbọn fún wọn lò. Nígbà tí àṣírí ọ̀kan nínú àwọn ọ̀daràn ọ̀hún (ìyẹn Ẹ̀gbọ́n) tú, pẹ̀lú ìtìjú tó ga ni ọ̀kan nínú àwọn ọ̀daràn náà fi sọ pé nípa Akilápá pé:

'Irú àwọn Akilápá yìí ní ń kó èérí bá iṣẹ́ ọlọ́pàá, àwọn àwọn ọ̀bàyéjẹ́ tí ń kó èérí igi yí obì iṣẹ́ ọlọ́pàá. Àwọn èèpò tí ó ń ba àlìkámọ̀ ìgbìyànjú iṣẹ́ ọlọ́pàá jẹ́' (*Oyin inú àpáta:*71-72)

Olúmúyíwa nínú ìwé ìtàn àròsọ rẹ̀ *Oorun orí kẹ̀kẹ́* jẹ́, ká mọ ewu tó wà nínú kí àwọn òbìlẹ̀jẹ́ wà láàárin awùjọ kan. Èyí wáyé nígbà tí kọmiṣọ́nà Ìdòwú ń ṣàfihàn àwọn òbìlẹ̀jẹ́ ọlọ́pàá àárín wọn fún àwọn ońròyìn. Ó wí pé:

'Awọn ọlọ́pàá tí ẹ̀ ń wò yìí ni ọmọ ọsàn tó ń kó kóńdó bá ìyá. Àwọn lòbu la̍árín ẹyin. Àwọn ló ń ba iṣẹ́ ọlọ́pàá jẹ́'. (*Oorun orí kẹ̀kẹ́*:116)

Nínú àwọn ìwé eré-onítàn àṣàyàn wa, ọ̀rọ̀ nípa àwọn òbìlẹ̀jẹ́ yìí náà kò ṣàì jẹyọ. Fún àpẹẹrẹ, Ògúnníran nínú ìwé eré-onítàn rẹ̀ (Ọ*lọrun ò màwàdà*: 60-66), pariwo síta pé àwọn ọlọ́pàá ń gbàgbọ̀dè. A fìdí èyí múlẹ̀ nínú ẹ̀dá ìtàn Kọmíṣọ́nà Ajẹunsínúdekú tó pàdí àpò pẹ̀lú òṣìṣẹ́ abẹ́ rẹ̀ Ìǹsìpẹ́kítọ̀ Ìjàòdọlà láti dojú ìwádìí ẹjọ́ ìpànìyàn kan tí wọ́n ń ṣe lọ́wọ́ rú. Adélékè, nínú ewì rẹ̀ *Irúkírú ọlọ́pàa* náà jẹ́rìí sí kókó ọ̀rọ̀ yìí. Ó fi ẹ̀sùn kan àwọn ọlọ́pàá pé wọ́n ń gbàgbọ̀dè àti pé wọn kìí ṣe ọmọlúàbí. Ó ní:

'Wọ́n kẹrán mérò nísẹ́ ọlọ́pàá
Gbogbo ìlú ò fararọ
Kànràn kọlọ́pàá gbófinró
Mọ́gàjí arúfin lọlọ́pàá dà'. (*Aṣọ ìgbà:*64)

Nínú ewì tí a dárúkọ lókè yìí, Adélékè nígbà tó ń sọ nípa George Ìyámù (ẹnikan tó ti figbà kan jẹ́ ọlọ́pàá rí lórílẹ̀-èdè Nàìjíría) tẹ̀ síwàjú pé, èpò ń bẹ nínú àlìkámà àwọn ọlọ́pàá. Ó ní:

'Bá à mọ gbogbo rẹ̀
A rántí Ìyámù l'Ádó Ìbíní
Ìyámù olórí ọlọ́pàá
Tó dagbódegbà àwọn ìgárá' (*Aṣọ Ìgba*: 65)

Ìtàn òkè yìí ni Gbénró fi ọgbọ́n àgbélẹ̀rọ̀ ṣàgbékalẹ̀ nínú *Atítẹ̀ẹ́bí* lára ẹ̀dá ìtàn kan tó jẹ́ ọlọ́pàá ìyẹn, Àjàmú. Kì í ṣe pé Àjàmú dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ adigun-jalè Àmọ̀sá nìkan ṣùgbọ́n, a tún máa kó aṣọ ọlọ́pàá àti àwọn ohun ìjà ijọba fún wọn láti lò. Òǹkọ̀wé ní:

'Ìgbà tí Àmọ̀sá búra fún Àjàmú tán ni ó ṣe àlàyé ohun tí àwọn ń ṣe àti ipa tí ó fẹ́ kí Àjàmú kó… Ó sì gbà láti máa bá wọn wá ìbọn àti àwọn aṣọ ọlọ́pàá nígbà tí iṣẹ́ bá yá' (53).

Àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé irú àwọn òbìlẹ̀jẹ́ ọlọ́pàá báyìí kì í ṣe ọmọ orílẹ̀-èdè gidi. Ní ọ̀nà àti wà ojútùú sí ìpènijà yìí, Adélékè nínú àkójọpọ̀ ewì *Aṣọ ìgbà*, ní pàtàkì, *Irúkìírú ọlọ́pàá* dá a lábàá pé:

'Gbogbo èpò tí ń bẹ pátá
Ẹ yọ wọ́n dànù bí i jìgá
Kíyì lè báṣẹ́ ọba.' (*Aṣọ ìgbà:*66)

Nínú àkójọpọ̀ ewì tirẹ̀ náà, ìyẹn *Orin ewúro*, ní pàtàkì nínú *Àdáàkó àjọ,* Àtàrí Àjànàkú ní ṣe ló yẹ ká máa yẹgi fún àwọn òbìlẹ̀jẹ́ ọlọ́pàá náà ní gbangba gẹ́gẹ́ bí a ti ń ṣe fún àwọn adigunjalè. O ní:

'Ìdigunjalè kan ò jùyí
Gbogbo yín ló yẹ kó fẹ̀yìn tàgbá' (*Orin ewúro:*42)

Lákòótán, àkéwì tẹ̀ síwàjú nípa gbígba àwọn ará ìlú nímọ̀ràn pé kí àwọn náà jí gìrì láti gba ara wọn kalẹ̀ nínú ìgbèkùn àwọn ọlọ́pàà jẹgúdújẹrá. Ó kégbe pé:

'Àwa ló yẹ ká ṣara gírí
Ká jára gbà...
Agbófinró kan kò sí
Tó ju ará ìlú lọ. (*Orin ewúro:*42)

## 5.0 Ìgúnlẹ̀

Kókó tí iṣẹ́ ìwádìí ṣàgbéyẹ̀wò ni àwọn ìpènijà tó ń dí àwọn ọlọ́pàá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà lọ́wọ́ lẹ́nu iṣẹ́ wọn. Àwọn ìpènijà yìí ló fẹ̀rẹ̀ẹ́ dàbí adígbọ́nákú fún àwọn ọlọ́pàá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà lẹ́nu iṣẹ́ òòjọ́ wọn, tí ó sì ń jẹ́ kí awùjọ máa fojú aláìmọ̀ọ̀ṣe wò wọ́n. Lára àwọn ìpènijà tí a hú jáde tí a sì ṣàtúpalẹ̀ ni: ọ̀rọ̀ akọ-n-bábo, àìní ìlapa ètò òun irinṣẹ́ tó mú yányán, àìsí ètò amáyédẹrun tó fún àwọn ọlọ́pàá, irú ìjọba tàbí àwọn olórí ọlọ́pàá tó wà lóde àti ìwà òbìlẹ̀jẹ́ láààrín àwọn ọlọ́pàá fúnra wọn. A ṣe àfàyọ àwọn àyọlò tó fìdí kókó ìwádìí yìí múlẹ̀ jáde láti inú àwọn lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ tí a ṣàyàn, a sì ṣe àtúpalẹ̀ wọn. Iṣẹ́ ìwádìí

yìí gbà pé, tí a bá lè wá ojútùú sí àwọn ìpènijà òkè yìí, àwọn ọlọ́pàá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà yóò lè túbọ̀ ta bíọ̀biọ̀ sí i lẹ́nu iṣẹ́ wọn, àwùjọ wa yóò sì tùbà tùṣẹ. Ìyẹn ni pé, kí ìjọba mú ayé dẹrùn fún àwọn ọlọ́pàá, kí àwọn ọlọ́pàá fúnra wọn sì yàgò fún ìmẹ́lẹ́ ṣíṣe àti ìwà òbìlẹ̀jẹ́ láàárin wọn. Parípari rẹ̀, kí Àjọ tó ń ṣàkóso àwọn ọlọ́pàá gbìyànjú láti gba àwọn obìnrin sínú iṣẹ́ ọ̀hún sí i, kí wọ́n sì fún àwọn ti ìṣe wọn bá tayọ láǹfàání láti di àwọn ipò gíga mú.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adélékè, D. *Aṣọ Ìgbà.* Abẹ́òkúta, (Nigeria): Visual Resources Publishers, 1997.

Adékọ̀lá, Moses. "The Nigeria Police and You". A paper presented at the First Baptist, Ọ̀yọ́, Ọ̀yọ́, State, (Nigeria). March 25th, 2018.

Adégòkè, T. G. "Effects of Occupational Stress on Psychological Well-Being of Police Employees in Ìbàdàn Metropolis, Nigeria". Unpublished doctoral dissertation, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn, (Nigeria), 2014.

Adéyemí, L. *Ọ̀dájú ni wọ́n.* Ìbàdàn: Extention Publications Limited, 2017.

Adéyẹmí, L. *Tíọ́rì Lítíréṣọ̀ Ní Èdè Yorùbá.* Ìjẹbú-Òde: Shebíotimọ̀ Publications, 2006.

Àjàyí, T. M. "(Im)Politeness Strategies and Power Abuse In Police Suspect Interrogation In Ibadan, Nigeria". Unpublished Ph.D thesis, University of Ibadan, Ibadan (Nigeria), 2016.

Akíntókun, G. *Gbamúgbamù.* Iléṣa (Nigeria): Elyon Publisher, 2006.

Àrẹ̀mú, A.O. *The 'Trinity' And The Missing Mission in Policing*. An Inagural Lecture delivered at the University of Ìbàdàn, Ìbàdàn (Nigeria). May 18th, 2017.

Àrẹ̀mú, A.O. "Policing And Terrorism, Challenges and Issues In Intelligence". Ọ̀yọ́ (Nigeria): Sterling Horden Publishers Ltd, 2014. Àrẹ̀mú, A.O. *Understanding Nigeria Police: Lessons from Psychology Research.* Ìbàdàn (Nigeria): Spectrum Books Ltd, 2009.

Àtàrí, A. *Orin Ewúro.* Ìbàdàn (Nigeria): Atlantis Books, 2004.

Brownson, B.O. "The Role of Nigeria Police Force In The Administration of Justice: Issues And Challenges". Unpublished LLM thesis, Ahmadu Bello University, Zaria, (Nigeria), 2012.

Búsàrí, B, et al. *Imaging The Nigeria Police, A Public Perception*. Ibadan (Nigeria): Right Medium Communication, 2015.

Gbénró, D. *Atítẹ̀ẹ́bí.* Ìbàdàn (Nigeria): Extention publications limited, 2017.

Fátùrótì, O. R. "Àyẹ̀wò Ipa Tí Àwọn Ọlọ́pàá Kó Nínú Ìwé Ìtàn Àròsọ Yorùbá." An Unpublished M.A thesis, Department of African Languages, University of Ifẹ̀, (Nigeria), 1998.

Ìṣọ̀lá, A. *Ayé Yẹ Wọ́n Tán.* Ìbàdàn (Nigeria): DB Martoy Books, 2009.

Ògúnníran, L. *Ọlọ́run Ò Màwàdà.* Ìbàdàn (Nigeria): Frontline Publishers, 1991..

Òkèdìjí, O. *Àjà Ló Lẹrù.* Ìkẹjà (Nigeria): Longman Plc, 2000.

Ọlábímtán, A. *Olúwa Ló Mẹjọ́ Dá*. Ìbàdàn (Nigeria): Macmillan Nig Publishers Ltd, 2005.

Ọlátẹ́jú, A. *Iná Ràn.* Ìbàdàn (Nigeria): DB Martoy Books, 2009.

Olongha, S. "The Role of The Nigeria Police In The Maintenance of Peace and Security." Retrieved from: samuelolongha.blogspot.co.ke/2016/06/role-of-nigeria-police-in-maintenance.html? m = 1. 2016.

Olúmúyíwá, T. *Oorun Orí Kẹ̀kẹ́.* Lagos (Nigeria): The Capstone Publications, 2008.

Owólabí, O. *Oyíndàmọlá Ọmọ Ọlọ́rọ̀.* Ìbàdàn. (Nigeria): University Press, 1981.

Sydney-Agbor Ngozi, et-al. "The Work Ethical Behaviour of Nigeria Police Officers as a Function of Self-Esteem, Gender and Age." In *British Journal of Education, Society & Behavioural Science*. 3.3 2013: 335-344. Retrieved from www.sciencedomain.org Retrieved on August 10, 2016.

Ṣóẹ̀tán, S. *Oyin Inú Apáta*. Abẹ́òkúta (Nigeria): African Resource Communications, 2006.